# Alaye fun awọn Obi ati Alagbatọ

## Ọrọ asọṣaaju fun awọn Obi/Alagbatọ ati Oluṣọ awọn Ọdọ

**Kin-ni Connexion…**
Connexion ni iṣẹ atilẹyin ti orilẹ-ede fun gbogbo awọn ọdọ lati ọmọ-ọdun mẹtala titi de ọmọ-ọdun mọkandinloogun (13 – 19), ati titi de ọmọ-ọdun marunleloogun (25) fun awọn ọdọ ti o ni iṣoro lati ka iwe, ti wọn ko si ni agbara to peye lati kọ ẹkọ.

Connexions ma nfun awọn ọdọ ni imọran, itọsọna ati atilẹyin lori awọn ọrọ kan bii eto-ẹkọ, idanilẹkọ, iṣẹ, ipinnu nipa owo ati igbe-aye ẹni, ki a baa le ran wọn lọwọ ki idagbasoke wọn si agbalagba, ati si igbe-aye iṣẹ-ṣiṣe ba a le ja geere.

Awọn obi ati Alagbatọ nikan ni o ni ipa ti o pọ julọ lori ipinnu ti awọn ọdọ yoo ṣe nipa ọjọ iwaju wọn, nitori naa ni o ṣe ṣe Pataki fun ọ lati mọ awọn iranlọwọ ti o wa fun awọn ọdọ nipasẹ Connexions.

**Bawo ni Connexions ṣe le ran ọmọ mi lọwọ?**

Gbogbo ọdọ le ni pade pẹlu Oludamọran ti ara-ẹni, ti yoo fun wọn ni atilẹyin, imọran, ati itọsọna lori awọn ọran loriṣiriṣi, eyi ti o kan eto-ẹkọ, igbe-aye iṣẹ ẹni, iṣẹ ati idanilẹkọ, eto ilera, eto ile-gbigbe, owo ati awọn anfaani rẹ, fifi ara-ẹni ji fun iṣẹ, anfaani fun idagbasoke ati ṣiṣe faaji.

Ni afikun, awọn ọdọ le gba imọran ati alaye lati ọdọ Central London Connexions ati lati awọn aaye ayelujara awọn alaṣẹ ibilẹ, ati lati awọn Ibi-itaja Atẹṣẹduro Connexions ti o wa ni gbogbo agbegbe naa.

Connexions Direct npese ipa-ọna ti o yara pupọ, ti o si rọrun si imọran lati ọdọ awọn akọṣẹmọṣẹ, lati agogo mẹjọ owurọ si meji ọsan (8am – 2am), ni ọjọ meje (7) lọsẹ, nipasẹ ipe si **080 800 13 2 19** tabi nipa kikọ ọrọ ranṣẹ si **07766 4 13 2 19**, iwiregbe lori ayelujara tabi i-meeli wa ni **www.connexions-direct.com**.
Iṣẹ yi wa fun awọn Obi ati Alagbatọ pẹlu.

Oriṣi itọnisọna ati atilẹyin yoo ma yipada bi aini awọn ọdọ ni akoko kọọkan ṣe nyipada.

Lara awọn wọnyi le jẹ:

- Riran ni lọwọ lati yan eto ẹkọ fun ile-iwe giga, ati lati kọwe beere fun eto naa
- Riran ni lọwọ lati wa iṣẹ tabi idanilẹkọ, ati lati di iṣẹ tabi idanilẹkọ naa mu ṣinṣin
- Atilẹyin ni awọn ile ẹkọ giga lati ran awọn ọdọ lọwọ lati pari ẹkọ wọn
- Imọran nipa owo ti a o fi tọju ara-ẹni ni ile-ẹkọ giga
- Imọran nipa awọn ohun ti a le ṣe ni akoko ti ṣi silẹ, eyi ti o le ran ni lọwọ lati mu imọ ẹni gberu sii
- Riran ni lọwọ nipa anfaani gbogbogbo ti o tọ si ni, tabi nipa itọju ọmọ ẹni

- Imọran ati atilẹyin lori eto ile-gbigbe tabi awọn ohun miiran ti o kan ni, bi eto ilera tabi egbogi, eyi ti o le nii ṣe pẹlu agbara ọdọ lati le ka iwe, lati le kọ ẹkọ tabi lati le ṣiṣẹ.

Erongba Connexions ni lati ran ọmọ rẹ lọwọ lati ni imọran ati atilẹyin ti wọn nilo fun aṣeyọri ninu awọn igbesẹ wọn.

**Nibo ni ọmọ mi ti le ri Connexions?**

Awọn Oludamọran ti ara-ẹni ti Connexions le wa ni ile-ẹkọ, ile-iwe giga, ni ibi eto ikọṣẹ ati awọn agbekalẹ eto fun ọdọ.

Ibi-itaja Atẹṣẹduro Connexions wa ni agbegbe kọọkan, eyi ti o wa fun ọmọ rẹ lati kan si.

Lati ni imọ siwaju sii nipa iṣẹ Connexions ti o wa ni aarin ilu London, lati ṣe awari ipo ile-iṣẹ naa ni agbegbe rẹ, tabi lati kan si wa, lọ si: www.centrallondonconnexions.org.uk

Alaye yi wa ni ẹda akọsilẹ miiran, jọwọ pe 020 7938 8080.
Bi o ba ni ohunkohun lati sọ lori atẹjade yi, fi i-meeli ṣọwọ si: info@centrallondonconnexions.org.uk

## Ibi-itaja Atẹṣẹduro Connexions ni aarin ilu London

Orukọ Agbegbe, Adirẹsi & Tẹlifoonu

**Camden**
West Euston One Stop Shop,
Corner of Hampstead Road
and Robert Street, Camden,
London, NW1 3ED
020 7388 6007

Connexions Camden Centre,
78 Parkway, Camden,
London, NW1 7AN
020 7482 3996

**Islington**
White Lion Centre,
43-45 White Lion Street,
Islington, London, N1 9PW
020 7527 7031

**Kensington and Chelsea**
Connexions Centre, 125 Freston Road,
London, W10 6TH
020 7938 8008

**Lambeth**

Connexions Centre, 1-5 Acre Lane,
Brixton, London, SW2 5TB
020 7326 7642

**Southwark**
Connexions Centre,128 Rye Lane,
Peckham, London, SE15 4SB
020 7358 2160

Faces in Focus, 102 Harper Road,
Elephant and Castle, London, SE1 6AQ
020 7403 2444

**Wandsworth**
Connexions Centre, 17 Falcon Road,
Battersea, London, SW11 2PJ
020 7326 8700

Connexions at Tooting Base,
74-80 Upper Tooting Road, Tooting,
London, SW17 7PB
020 8682 9457

Connexions at Roehampton Base,
33-35 Danebury Avenue, Roehampton,
London, SW15 4DQ
020 8780 5253

**Westminster**
Connexions @ Stowe, The Stowe Centre,
258 Harrow Road, London, W2 5ES
020 7266 8230

Connexions @ Pimlico, 131 Lupus
Street, London, SW1V 3EN
020 7641 2069

Lọ si www.centrallondonconnexions.org.uk lati mọ awọn akoko ti awọn wọnyi ma nwa ni ṣiṣi.

Oṣu kẹjọ ọdun 2009